ATAKI
TO YANI
LẸNU




Baba Ẹjọọ.
Tunde ati Rọlakẹ kilode bayi?
Njẹ ẹranti pe ẹti se ileri lati sọ itan t'ose pataki julọ fun wa?
Bẹẹni! Itan eyiti o se pataki julọ on na ni ari ninu iwe ti o se pataki julọ, eyi ni Bibeli, Iwe Ọlọrun.
Se itan Bibeli?
Ki ise itan Bibeli lasan. Itan gbogbo Bibeli ni – Eyini ni eto Ọlọrun fun ẹda.
Bawo ni ase le mọ daju pe Bibeli jẹ Iwe Ọlọrun?


Njẹ Ọlọrun nkọ iwe bi?
Ọlọrun lo awọn Ogoji ọtọọtọ enia. Awọn wọnyi ni nwọn kọ Bibeli ni iwọn ẹgbẹrun ọdun ati abọ. Bibeli ni awọn iwe ọtọọtọ ọgọta ole mẹfa. Ninu eyiti gbogbo wọn si se rẹmu, nwọn si jọ duro papọ dada. Ọlọrun nikan ni o le se iwe bẹ ẹ.
Bawo ni Ọlọrun ti ri gan-an?
Ọlọrun bikita pupọ nipa wa o si ndawa lohun nigbati a ba nbere fun iranlọwọ. Ọlọrun jẹ Mimọ, O si pe. Iwọ ko le ri Ọlọrun sugbọn On nriọ, O si mọ ohun gbogbo. Bẹni o si le se ohun gbogbo. Jẹki Baba yin sọ itan na iwọ yio si ri.
Ni igba atijọ, Ọlọrun da aiye ati ohun gbogbo ti owa ninu rẹ! Lẹhin na Ọlọrun da ọgba ajara kan ti anpe ni Edeni. Ọlọrun pese rẹ fun idi pataki ati awọn enia pataki kan.
**Awa ni yẹn o!**

# *Dida – Adamu ati Efa*

*Asayan ẹsẹ Bibeli: Gẹnẹsisi 1,2*

**Ọlọrun wipe, "Jẹki ada enia ni aworan ara wa gẹgẹ bi iri wa." Oluwa Ọlọrun si fi erupẹ ilẹ mọ enia; o si mi Emi Iye si iho imu rẹ; o si di alaaye ọkan.**

"Erupẹ Ilẹ?"

"Bẹni, Ọlọrun le se ohunkohun!"

**Oluwa Ọlọrun si wipe, "Ko dara ki ọkunrin na ki o nikan ma gbe. Emi yio se oluranlọwọ ti o dabi rẹ fun." Oluwa Ọlọrun si fi oorun ijika kun Adamu, o si sun. O si yọ ọkan ninu egungun iha Adamu, osi fi egungun iha ti o mu ni iha ọkunrin na mọ obinrin.**

Ọlọrun si mu Efa, obinrin na, tọ Adamu wa gẹgẹ bi aya rẹ.

**Li arin ọgba na ni Ọlọrun gbin igi iye si, ati igi imọ rere ati buburu. Sugbọn Ọlọrun fun Ọkunrin na ni ikilọ bayi pe: "Ninu gbogbo igi ọgba ni ki iwọ ki o ma jẹ, sugbọn igi imọ rere ati buburu ni iwọ ko gbọdo jẹ ninu rẹ nitori pe ọjọ ti iwọ ba jẹ ninu rẹ, kiku ni iwọ yio ku."**

Adamu Ati Efa si ngbe inu ọgba ajara na, nwọn si ni ayọ ati inu didun. Nwọn sunmọ Ọlọrun, nwọn si gbadun ati ma wa pẹlu Rẹ.

Sugbọn ni ọjọ kan...







# *Adamu ati Efa D'ẹsẹ*

*Asayan ẹsẹ Bibeli: Gẹnẹsisi 3*

Satani, ọta Ọlọrun, wa gẹgẹ bi ejo. Ko fẹ ki Adamu ati Efa ma wa pẹlu Ọlọrun ki nwọn si ma gbọran si lẹnu.

**O bi Efa l'ere wipe, "Njẹ otitọ li Ọlọrun wipe, ẹyin ko gbọdọ jẹ gbogbo eso igi ọgba?"**

**Obinrin na sọ fun wipe, awa a ma jẹ ninu eso igi ọgba, sugbọn eso igi nni ti o wa larin ọgba ni Ọlọrun ti wipe awa ko gbọdo jẹ ninu rẹ. Ọlọrun sọ wipe awa ko gbọdọ jẹ ninu rẹ tabi ki a fi ọwọ kan an, ki awa ki o ma ba ku."**

**"Ẹyin ki yio ku rara!" ni ejo na wi "Ẹyin yio da gẹgẹ bi Ọlọrun."**

**Obinrin na gba Satani gbọ. Eso na dara loju o si dun wo, o si dabi ẹni pe o le mu ni gbọn! Bẹni Obinrin na si...**

"RARA! ma jẹẹ, ma jẹẹ, Efa ma se jẹẹ!"

"Tunde, Imọran daradara ni eyi. Sugbọn obinrin na jẹ, bẹni Adamu pẹlu."

Lọgan, ẹru ba wọn. Wọn sa pamọ fun Ọlọrun nigbati o wa lati bẹ wọn wo ninu ọgba.

Wọn ti dẹsẹ nipa yiyan lati se aigbọran si Ọlọrun. Nitorina Ọlọrun ran wọn jade lọ kuro– ninu ọgba Edeni.


Oran wọn jade ẹwẹ? Eyi nipe Ọlọrun ko fẹran wọn mọ?
Ti o ba se wipe emi ni, n'ko ni f'eti si Satani!
Njẹ nwọn tun ri Ọlọrun loju mọ lẹhin eyi?


Aha! ẹ ni suru diẹ! Ọlọrun fẹran wọn sibẹ. Sugbọn o korira ẹsẹ. Ẹsẹ nya ni nipa kuro lọdọ Ọlọrun.
Kini idi ti Ọlọrun fi fi igi na sinu ọgba?


Ọlọrun fẹran Adamu ati Efa. O fẹ ki nwọn ni agbara lati yan funra wọn pe awọn yio fẹran Ọlọrun nwọn yio si ma se igbọran si I. Sugbọn kaka bẹ nwọn yan lati se aigbọran si Ọlọrun. Nwọn ko mọ bi o ti buru to lati yapa kuro lọdọ Ọlọrun.
Ati pe nitori nwọn yan lati sẹ, gbogbo awọn ti a bi lẹhin wọn na ti dẹsẹ asi ti yapa kuro lọdọ Ọlọrun pẹlu.
Eyi ni nipe awa papa ko le ba Ọlọrun gbe nitori tiwọn? Eyi ko dara!
Tunde, ki ise tori tiwọn nikan ni. Gbogbo wa ni ati sẹ nigbati a ba se ohun ti ko tọ. Sugbọn ẹtujuka. Ẹma se daamu. Ọlọrun ni eto pataki lati mu wa pada wa sọdọ Rẹ. Sugbọn o nilo ẹnikan ti o pe, ti ko si dẹsẹ rara, lati ku fun ẹsẹ wa.
Nigbati asiko to fun ohun gbogbo, Ọlọrun fa eto Rẹ yọ. Eto na bẹrẹ pẹlu Ọmọ kekere kan!



# *Abi Jesu*

*Asayan Ẹsẹ Bibeli: Matiu 1, Luku 2*

Ọlọrun fi Ọmọ Rẹ fun araiye ni ọmọ ọwọ nipasẹ Maria. O si yan Josefu lati ran Maria lọwọ ni titọju Ọmọ na. Nitoripe Ọmọ Ọlọrun ni Ọmọde na, a bi lailẹsẹ.

**Angẹli Ọlọrun si yọ si Josefu ninu ala. Angẹli na si wipe, "Maria yio bi Ọmọkunrin kan, iwọ yio si pe orukọ rẹ ni Jesu, nitoripe On ni yio gba awọn enia Rẹ la kuro ninu ẹsẹ wọn."** ("Jesu" tumọ si wipe Oluwa ngbala.)



Ki ato bi ọmọ kekere na, Joseph ati Maria ni lati lọ si Bẹtilẹhẹmu.

**Nigbati nwọn wa nibẹ, Maria bi ọmọ rẹ akọkọ, Ọkunrin.**

Ọlọrun ran awọn Angẹli lati sọ fun awọn enia nipa ibi Ọmọ Rẹ na. Nwọn wa lati ri ohun isẹlẹ na: Ọmọ Ọlọrun ti abi ni Ọmọ ọwọ.

"Jesu ndagba gẹgẹ bi ẹyin ọmọ kekere na."

"Baba, njẹ Jesu lọ si ile iwe bi? Njẹ onsire?"

"Bẹni, Tunde. Osi ngbọran si awọn obi Rẹ lẹnu. O nse ifẹ Baba Rẹ li ọrun pẹlu. Ko si dẹsẹ rara!"



## *Jesu Olukọni*

*Asayan ẹsẹ Bibeli: Luku 2, Matiu 22, Johannu 3*

Nigbati Jesu di Ọmọ ọdun mejila, owa ni Jerusalẹmu pẹlu awọn Olukọni.

**Ninu Tempili ni Owa ti O' nba awọn olukọni jiroro ohun ijinlẹ. Gbogbo awọn ti osi gbọ ọrọ Rẹ ni o ya lẹnu wipe Ọmọ na ni oye ninu gbogbo awọn idahun Rẹ.**

**Jesu ndagba ninu ọgbọn, osi nga si i, Ọlọrun fẹran Rẹ, ati gbogbo awọn ti o mọ pẹlu.**

Nigbati Jesu di Ẹni ọgbọn ọdun, o bẹrẹ si kọni osi nwasu. Jesu kọni wipe gbogbo awọn iwa ati ero wa ni Ọlọrun mọ. Siwaju si o wipe, **" 'Iwọ gbọdọ fẹran Oluwa Ọlọrun rẹ pẹlu gbogbo ọkan rẹ ati gbogbo aiya rẹ, ati gbogbo ẹmi rẹ.' Eleyi ni ofin akọkọ ti o tobi ju. Ekeji na si se pataki pẹlu: 'Fẹran arakunrin rẹ gẹgẹ bi ara rẹ.' "**

Jesu kọni nipa eto pataki ti Ọlọrun nse lati mu wa pada wa si ọdọ Rẹ.

On sọ wipe, **"Ọlọrun fẹran araiye tobẹ gẹ, ti ofi Ọmọ bibi Rẹ nikansoso fun ni, wipe ẹnikẹni ti o ba gba a gbọ, koni segbe sugbọn yio ni iye ainipẹkun."**

"Baba, mo gba Jesu gbọ!"

"Aaa, o seun Rọlakẹ!"





# *Jesu Oluwosan*

*Asayan ẹsẹ Bibeli: Matiu 4,9*

Jesu jẹki awọn enia mọ bi Ọlọrun ti ri. Ofi han wọn wipe Ọlọrun fẹran wọn. Ọna kan ti o se eleyi ni pe Onwo gbogbo oniruru arun ati aisan.

**Ọpọlọpọ awọn alailera ni nwọn tọ Jesu wa. Gbogbo oniruru aisan ati ailera wọn, tabi ẹmi buburu wọn, tabi arun ẹgba, tabi oniruru aisan–gbogbo rẹ ni Jesu wosan patapata.**

Ni ọjọ kan, Ijoye kan wa wolẹ niwaju Jesu.

**O wipe, "Ọdọmọbinrin mi ti ku, sugbọn iwọ le ji i dide ti iwọ ba le wa gbe ọwọ rẹ le e."**

**Jesu si lọ, O fa ọdọmọbirin na lọwọ, o si ji i dide!**

"Kinla! Baba mi se Jesu wo awọn enia san lootọ?"

"Bẹni, Tunde, bakanna ni O'nwoni san loni. Kosi ohun ti o soro se fun!"







# *Jesu Onisẹ Iyanu*

*Asayan ẹsẹ Bibeli: Matiu 14, Johannu 6*

"Awọn ọpọlọpọ isẹ iyanu ni Jesu se. Oda iji duro, o si rin lori okun!"

"A, eyi gbọdọ jẹ ohun iyalẹnu fun enia!"

"Bẹni, Tunde. Nigbakan, atilẹ ri ọpọ enia bi 5,000 ti nwọn tẹle Jesu lọ si ibikan ti o jinna diẹ. Lati ibẹ ni awọn ọrẹ ati Ọmọ Ẹhin Jesu fẹ lati ran awọn ọpọ enia na pada lọ si ile wọn nitoripe ọjọ ti lọ, ebi si npa wọn."

**Nigbana ni Jesu dahun o si wipe, "Ẹmase ran wọn lọ–ẹfun wọn ni ounjẹ."**

**Anderu dahun, o si wipe "Ọdọmọkunrin kan wa nihinyi pẹlu isu akara marun ati ẹja meji! Sugbọn kini a le fi iru ounjẹ kekere yi se larin ọpọ enia?"**

**Jesu gba isu akara na, o dupẹ lọwọ Ọlọrun, o si pin ounjẹ na larin awọn enia na. Bakanna ni ose pẹlu ẹja. Gbogbo awọn enia na si jẹ ajẹyo ati ajẹsẹku!**

**Jesu wa sọ fun awọm ọmọ ẹhin Rẹ wipe, "Nisisiyi ẹ lọ sa ounjẹ ti o sẹku, ki nkankan ma ba so'fo."**

**Isu akara marun ni afi bẹrẹ sugbọn awọn ajẹsẹku ti ari jẹ apẹrẹ mejila eyiti awọn enia na jẹ sẹku!**

"Njẹ awọn ajẹsẹku tun pọ ju ounjẹ ti nwọn fi bẹrẹ lọ?"

"Bẹni, Rọlakẹ. Jesu nkọwọn wipe Ọlọrun le pese gbogbo aini wọn. Bakanna, Ọlọrun yio si pese fun wa bi aba bere lọwọ Rẹ."






# *Jesu ati awọn Ọmọde*

*Asayan ẹsẹ Bibeli: Matiu 19, Marku 10*

"Jesu fi han awọn enia wipe Ọlọrun fẹran awọn ọmọde. O wo wọn san, o jẹki nwọn ran on lọwọ ninu isẹ Rẹ (gẹgẹ bi apẹrẹ, ọdọmọkunrin ti omu isu akara ounjẹ lọwọ) o si tun ji awọn oku dide!"

**Awọn ọmọde ni amuwa si ọdọ Jesu ki o le gbe ọwọ le wọn ki o si gbadura fun wọn. Nigbana ni awọn ọmọ ẹhin Rẹ wi fun wọn wipe ki nwọn mase da Jesu laamu, nwọn si fẹ dẹkun wọn.**



**Nigbati Jesu ri awọn ohun ti nṣẹlẹ, O sọ wipe, "Ẹjẹki awọn ọmọde kekere wa sọdọ mi, ẹmase da wọn lẹkun! Ẹnikẹni ti ko ba ni iru igbagbọ ti awọn ọmọde wọnyi ko le wọ Ijọba Ọlọrun." Nigbana ni Jesu si gbe wọn le apa Rẹ, O gbe ọwọ le wọn pẹlu, O si sure fun wọn.**

"Emi pẹlu fẹ ki Jesu sure fun mi!"

"Jesu le sure fun ọ, Tunde. Jesu kanna ni owa l'oni, o si fẹran awọn Ọmọ kekere sibẹ."

"Ki ise gbogbo enia ni nwọn fẹran Jesu. Ohun ti Jesu se ati ẹkọ ti Onkọni mu ki inu bi awọn olori ẹsin nigbana. Nwọn njowu wipe awọn enia fẹran Jesu to bẹẹ. Nitorina nwọn ngbimọ lati mu Jesu kuro."

# *A mu Jesu, Asi mu wa si iwaju Idajọ*

*Asayan ẹsẹ Bibeli: Luku 22, Johannu 19*

"Ni alẹ ọjọkan, nigbati Jesu nba awọn ọrẹ Rẹ sọrọ, ni awọn olori ẹsin ran ọpọ enia lati lọ mu Jesu pẹlu ida, ati ọkọ."

**Awọn ọmọ ẹhin Rẹ ke ni ohun rara wipe "Oluwa, se ki aba wọn ja? Awa ni ida nibiyi!" Lojukanna ni ọkan ninu awọn ọmọ ẹhin Jesu fi ida ge eti ọkan ninu awọn iransẹ ti owa mu Jesu. Sugbọn Jesu sọ wipe, "Ẹmase bawọn ja mọ." Nigbana ni O si fi eti iransẹ na pada si ipo, O si mu larada.**





"Jesu mu ọkan ninu awọn ọta Rẹ larada bi?"

"Bẹni, Rọlakẹ. Jesu fẹran gbogbo enia."

Bẹni nwọn fi tipa mu Jesu lọ si ọdọ olori ati alasẹ, Pilatu, nwọn si daA l'ẹjọ. Awọn ọmọ ogun na Jesu, nwọn fi ẹgun gun lori, nwọn si fi se eleya. Nigbana ni Pilatu sọrọ si awọn enia.

**"Emi yio mu jade fun yin wa nisisi, sugbọn ẹ mọ daju pe emi ko ri ẹbi kankan ninu Rẹ."**

**"Ẹmu lọ, ẹmu lọ kan an mọ agbelebu!" ni awọn enia na nke. "Kan an mọ agbelebu!"**

**Nigbana ni Pilatu fi Jesu le wọn lọwọ lati kaan mọ agbelebu.**

"Sugbọn Jesu ko se ohun buburu kan! Eyi ko tọ rara!"

"Bẹni, Tunde. Sugbọn ranti pe Ọlọrun ni eto Rẹ pataki."

# *Jesu ku lori igi Agbelebu*

*Asayan ẹsẹ Bibeli: Luke 23*

"Nwọn kan Jesu mọ agbelebu."

**Jesu si wipe, "Baba dariji awọn enia wọnyi, nitoripe nwọn ko mọ ohun ti nwọn nse."**

**Awọn arufin meji ni akan mọ agbelebu pẹlu Jesu. Ọkan ninu awọn arufin wọnyi lẹba Jesu nfi I sẹfẹ, wipe, "Bẹni iwọ ni Messiah abi bẹkọ?"** (Messiah ni orukọ ti anpe Ọmọ Ọlọrun.) **"Fi han wipe iwọ jẹ Ọmọ Ọlọrun, gba ara rẹ la nisisiyi – ati awa na pẹlu, ti oba le se bẹ!"**

**Sugbọn arufin keji da lohun wipe, iwọ kotilẹ bẹru Ọlọrun, nigbati iwọ nku lọ? Ijiya yi ati iku yi tọ si wa nitoripe ajẹ oluse buburu, sugbọn Ọkunrin yi ko se aida kankan." Nigbana ni osọ fun Jesu wipe, "Jesu, ranti mi nigbati iwọ ba wa si inu Ijọba Rẹ."**

**Jesu daa lohun wipe, "Dajudaju, loni ni iwọ yio wa pẹlu mi ni paradise."**

"Owa pẹlu Jesu lẹhin iku rẹ bi?"

"Bẹni, Rọlakẹ!"

"Lẹhin na ni Jesu kigbe ni ohun rara si Ọlọrun, o si ku."

"He e, se Jesu yi ni ẹnina ti owa ninu eto Ọlọrun?"

"Bẹni, Tunde. Ọlọrun ran Ọmọ Rẹ ti ope ti ko dẹsẹ, ani Jesu. O ku lati gba gbogbo iya ẹsẹ wa jẹ."





# *Jesu wa Laaye*

*Asayan ẹsẹ Bibeli: Matiu 28, Luke 24*

Oku Jesu ni awọn Ọrẹ Rẹ tẹ sinu iboji kan.

Ni owurọ ọjọ ọsẹ ni awọn obinrin meji kan sare lọ sibi iboji na.

**Lojiji ni isẹlẹ sẹlẹ, nitoripe angẹli Ọlọrun sọkalẹ lati ọrun wa, lati wa yi okuta na kuro lẹnu iboji.**

**O wifun wọn pe, "Ẹmase bẹru, momọ wipe ẹnwa Jesu ẹniti akan mọ agbelebu. Ko si ni ihin yi! Ati ji I dide kuro ninu oku bi O tisọ fun yin tẹlẹ ri. Nisisiyi, ẹlọ sọ fun awọn ọmọ ẹhin Rẹ."**



"Apa ti odun ju ninu itan na niyi!"

"Bẹni, Tunde! Lẹhin ti o san gbogbo gbese ẹsẹ wa ni Ọlọrun ji I dide kuro ninu oku. Eleyi jẹ eto Ọlọrun lati ibẹrẹ."

Lẹhin eyi, nigbati awọn Ọmọ Ẹhin Jesu nsọrọ nipa iku ati ajinde Rẹ, **Jesu yọju si wọn lọgan o si duro larin wọn. O wipe, "Alafia fun yin." Sugbọn gbogbo awọn enia na ni ẹru ba, nitoripe nwọn ro wipe awọn nri oku ni!**

**Jesu wa bere lọwọ wọn wipe, "Kini idi ti ẹru fi nba yin? Ẹwo ọwọ mi. Ẹwo ẹsẹ mi pẹlu. Se ẹri nisisiyi wipe emi tikara mi ni. Ẹfi ọwọ kan mi ki ẹsi mọ wipe daju ki ise oku bikose alaye!"**





# *Nibo ni Jesu wa Loni?*

*Asayan ẹsẹ Bibeli: Johannu 16, Ise Awọn Aposteli 1*

"Jesu wa pẹlu awọn ọmọ ẹhin Rẹ ni iwọn ọsẹ pupọ."
"O ni lati jẹ wipe inu wọn dun pupọ, nwọn si l'ayọ!"
"Bẹni, sugbọn nibo ni Jesu wa loni?"
"Ibere yi dara pupọ, Rọlakẹ."
Jesu sọ wipe, **"Odara nitori tiyin pe ki nlọ, nitoripe ti emi ko ba lọ Ẹmi Mimọ ko le wa. Sugbọn ti mo ba lọ, On yio wa, nitoripe emi yio fi ransẹ si yin."**



Nigbati Jesu ti pari ọrọ wọnyi ti osọ fun awọn ọmọ ẹhin Rẹ, si wo o, ongoke lọ si ọrun, asi gbaa kuro loju wọn sinu awọsanmọ. Nigbana ni awọn Angẹli meji sọ fun wọn wipe, **"Ati gba Jesu kuro lọdọ yin lọ sinu Ọrun. Sugbọn ijọ kan mbọ nigbati yio pada wa gẹgẹ bi ẹti ri ti ongoke lọ!"**

Ni Ọjọ kan ni Jesu yio pada wa lati mu gbogbo awọn Ọmọ Ọlọrun. Eyi ni gbogbo awọn enia ti nwọn gbagbọ pe Jesu ku fun wọn, ti asi ti dari ẹsẹ wọn ji wọn. Awa yio si wa Pẹlu Rẹ lailai. Kosi si ohun kan ti yio ya wa kuro ninu ifẹ Ọlọrun mọ!


Emi fẹ di ọmọ Ọlọrun, ki nle wa pẹlu Rẹ lailai.
Eyi dara, Tunde! Eleyi jẹ ipinnu ti ose pataki julọ ti iwọ ti se! Bibeli sọ fun wa wipe, ẹsẹ wa ni o ya wa nipa kuro lọdọ Ọlọrun. Bẹni o tun wipe, "Ti iwọ ba jẹwọ pẹlu ẹnu rẹ, wipe Jesu ni Oluwa ti o si gbagbọ pẹlu ọkan rẹ, wipe a ti ji I dide kuro ninu oku, ao gbaọ la. Nitoripe nipa fifi ọkan rẹ gbagbọ ni a se mu ọ wa li alafia pẹlu Ọlọrun, ati pe nipa fifi ẹnu rẹ jẹwọ ni ase gba ọ la." *Romu 10:9-10*
Emi le sọ bẹ! Nitoripe dajudaju mo gbagbọ ninu Jesu!
Bi oba ribẹ ẹjẹki a sọ fun Ọlọrun. Ọlọrun ntẹti si wa ni gbogbo igba, Tunde. Ọlọrun ngbọ adura, O si nda wa lọohun. Gba adura yi pẹlu mi.

Ọlọrun, mo mọ wipe emi jẹ ẹlẹsẹ. Mo si ti siyan, mo ti se awọn ohun buburu pupọ. Mo jẹwọ ẹsẹ mi. Jọwọ dariji mi. Mo mọ pe Ọmọ Rẹ kan soso Jesu ti ku nitori ẹsẹ mi, mo si gbagbọ pe O ti ji Jesu dide kuro ninu Oku. Mo fẹ ki Jesu jẹ Oluwa mi. Mo dupẹ fun ifẹ Rẹ eyiti o mu mi di Ọmọ Ọlọrun. Nisisiyi jọwọ fi Ẹmi Mimọ Rẹ kun mi ki nle ni agbara ati okun lati le ma se igbọran si Ọ. Amin.






Kinla! Emi ti di Ọmọ Ọlọrun nisisiyi, abi bẹkọ?
Laise aniani, bẹni!
Nisisiyi ki iwọ le tubọ mọ Ọlọrun siwaju si i, o yẹ ki o ranti lati ma gbadura si I, ki o si ma ba A sọrọ, ki o si ma ka nipa Rẹ ninu Iwe Rẹ Mimo ti anpe ni Bibeli. Ọlọrun mba ọ sọrọ lati inu Bibeli wa, O si nsọ awọn ohun pataki ti O fẹ ki ose.
Baba, kini awọn nkan wọnyi?
Lati fẹ Ọlọrun, lati ma sọ fun awọn enia nipa Jesu, ati lati fi ifẹ ati agbara nla Ọlọrun han wọn.
Jesu sọ fun awọn Ọmọ Ẹhin Rẹ wipe, "Ẹ lọ si gbogbo aiye ki ẹsi sọ awọn enia di Ọmọ Ẹhin mi... Ẹkọ wọn lati se igbọran si gbogbo awọn ofin ti mo ti pa lasẹ fun yin. Ẹsi mọ eyi daju pe, Emi wa pẹlu yin nigbagbogbo."
*Matiu 28:19-20*


Lẹhin ti Jesu ti lọ si Ọrun, O ran Ẹmi Mimọ. Oun yio ma tọ ọ, yio si ma kọ ọ , yio si fun ọ ni agbara Ọlọrun lati fi jẹri fun awọn ẹlomiran.
Mofẹ lati sọ fun awọn ọrẹ mi!
Gbọ! ohun ti o dara julọ ti sẹlẹ si mi! O si le sẹlẹ si iwọ na pẹlu! Nitori pe iwọ paapa le gbagbọ ki o si gbe igbesẹ kanna ti emi ti gbe! Gbadura, Ọlọrun yio si gbọ adura rẹ. Ọlọrun fẹran rẹ, yio dariji ọ, yio si sọ ọ di Ọmọ Rẹ.

***"Iwọ wo Iwe Ọlọrun (Bibeli) ki o si bẹrẹ irinajo igbesi aiye rẹ ti o se pataki julọ!"***



Copyright © 1996 WorldServe Ministries
Enikẹni ko gbọdọ tẹ iwe yi jade laigba asẹ

A tẹ iwe yi lakọkọ ni ede Yoruba, ni ọdun 1998

WorldServe Ministries ni a ti ọwọ wọn tẹ iwe yi jade, ni Sri Lank[illegible]

ISBN 1 896658 22 9 *Yoruba*

YORU 504